# ÌWÉ – ÀFÉNUKÒ ÀWON OHUN TÍ A N Fé:

## OHÙN ÀWON OBÌNRIN – ONÍSÒWÒ OYÓ



Iyamopo Centre for Peace, Women and Youth Development, Ibadan

# Ọ̀rọ̀ – Àsọtẹ́lẹ̀.


Àwa obìnrin-Onísòwò ti Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ – jẹ́ abiyamọ, olùpèsè fún ìdílé wa, olùdásẹ́sílẹ̀, ati olùpamọ́ ọrọ̀-ajé agbègbè àti ìgbériko – dìde ní ìsọ̀kan bèrè fún àpọ́nle, ìgbélárugẹ àwọn ẹ̀tọ́, àti àwọn ohun àmúsagbára to se déédé pẹ̀lú gbogbo ojuse àti ilọwọsi wa fún ìlọsíwájú, ìdàgbàsókè, àti isọkan àwùjọ. Pẹ̀lú ipa takun-takun tí àwa obìnrin ońisòwò ń kó lórí ìpèsè àti ètò pín-pín oúnjẹ ní



Orisun: Akintunde Akinleye/Reuters.

Ẹsẹ̀-kùkú, ìlú-kéréje, àti àwọn ìlú-ńlá ni ìpínlẹ̀ yi àti gbogbo orilede Nàìjíríà, ọjà tita ni abẹ́lé ati ìgbélárugẹ alaafia àti ìgbáyé-gbádùn ẹbí àti àwùjọ, pẹ̀lú gbogbo ìgbìyànjú wa yii, a ni ìsòro àti àdojúkọ ìwà ìyàsọ́tọ̀ àtọlẹ̀dọ́lẹ̀ àti ìnira.

Fún àimọye ọdun, àwa obìnrin onísòwò ti jẹ́ òpòmúléró fún ọrọ̀ ajé ilẹ̀ fún ọrọ̀ ajé ilẹ̀ Yorùbá, àwùjọ àti gbogbo orílèdè naijiria – a ń se ìrólágbára àwùjọ, àkoso ìsúná mọ̀lẹ́bí, a ní ipa nínú ìse-akoso awujọ ní ìjọba ibilẹ, ipinlẹ àti orilede wa. Lati orí àwọn iyalọja tí wọ́n ti kó ipa takun-takun lórí ètò ìsèlú, títí dé orí gbogbo àwọn obìnrin tí wọ́n jẹ́ opómúléró fún idile wọn, àwa obìnrin ti kópa tó yanjú nínú àtúnse ọrọ-ajé, ìsèlú, ìtàn àti ọjọ́ iwájú àwùjọ wa.




Àwọn obìnrin onísòwò ní orílèdè Naijiria bótilẹ̀jẹ́pé ìjọba ń fi ojú fòwá, a n kópa tó jọjú nínú ètò ìsèlú ni ìjọba ìbílẹ̀ àti ìjọba àpapọ̀. Olùkópa pàtàkì ni wá níbi síse kóríyá fún àwon olùdìbò, síse iranlọ́wọ́ fún ìkẹ́sẹjárí ètò ìdìbò lọ́jọ́ ìdìbò, àti gbígba ìjọba ní ìmọ̀ràn lórí àwọn àkànsè ètò tó kan àwọn ènìyàn ìgbèríko. Àwọn olósèlú ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ní ìgbẹkẹ̀lé lórí àtìlẹyìn wa lati se kóríyá fún àwọn olùdìbò, ní pàtakì jùlọ ní ìgbèríko àti ẹsẹ̀ kùkù.

Àwa obìnrin onísòwò ǹ se àtìlẹyìn fún ìmúgbooro ètò ìsèlù ní ìjọba ìbílẹ̀ fún ìdàgbàsókè ìgbèríko. Loni, kii se wípé, gbogbo ìgbìyànjú wa ni ó ti di pípare nínú ìwé ìtàn àwọn akíkanjú àti àwọn ènìyàn pàtàkì lásán, kódà ìjọba kò gbe wa sí fi àyè wa gẹ́gẹ́ bí ẹ̀tọ́ wa nínú ìsèlú ìjọba alagbádá, ìrónilágbára okòòwò, ati ètò àtúnse ìlọsíwájú. Fún ìgbà pípẹ́ ni àwa onísòwò ti ń kojú Ìwà ìdẹ́yẹsí, ainitọ́jú, ȁilàkàsí àti ìyanisọ́tọ̀ lọ́dọ̀ ìjọba.




Orisun: AP Photo - Sunday Alamba.

***Ìwé Àfẹnukò àwa obìnrin onísòwò yii jẹ́ ìpè fún ìdápadà iyì, ìfàmọ́ra, ati ìrànlọ́wọ́ fún àwọn obìnrin onísòwò ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, tí ohùn àti ìgbésíayé wọn se kókó àti pàtàkì.***

A gbé iwé Àfẹnukò yii kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìpè fún idajọ òdodo, dọ́gba-dọ́gba, ìse-déde, àjọsepọ̀ àti àtìlẹ́yìn gbogbo ìgbà lati ọ̀dọ̀ gbogbo ẹ̀ka ìjọba, ní ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀, àwọn aládáni, àwọn oríadé, àti gbogbo àwùjọ ní orílèdè yi àti gbogbo àgbáyé.

# I. ÌTÀN PÀTÀKÌ NIPA AKIKANJU ÀWON OBÌNRIN ONÍSÒWÒ


Orisun: Yorubaness.com {image extract from article written by Akinlolu Da Vinci}

- Ní ilẹ̀ Yorùbá àwọn obìnrin-onísòwò, ní pàtàkì jùlọ ní àwọn ìlú ńlá bí Ìbàdàn, Èkó, àti ìlú Òyó, ní àtijọ́ jẹ́ asíwájú nípa kíkọ̀ ìwà ìjẹgàba àti àwọn àsejù àwọn òyìnbó amúnisìn, àti àwọn ìlànà àti ètò tó ń fa ìnira fún àwọn ará ìlú. Saájú kí àwọn Òyìnbo amúnisìn too dé ni àwọn obìnrin onísòwò ti n kópa to jọjú nínú ìsèlú awujọ wa, wọ́n kópa tó se kókó ní àsìkò tí orílèdè wa ń se akitiyan lati gba òmìnira lọ́wọ́ orílède gẹẹsi, lẹ́yìn òmìnira, lásìkò ìjọba àwọn oloogun, àwọn obìnrin ọlọ́jà ko gbẹ́yìn nínú ètò àtúntò ìsèlú, ọrọ̀-ajé.
- Àwọn obìnrin onísòwò tó wa ní àwọn olú-ìlu bi Ìbàdàn nígbàkan ti jẹ́ orísun agbára àti apàsẹ, lórí àwọn ọ̀rọ̀ to kan ìlu, ọmọnìyàn àti agbègbè won. Àwọn akíkanjú obìnrin bii Ìyalode Efúnsetán Aníwúrà pẹ̀lú àwọn ìgbìmọ̀ ìyálọ́jà ti wọn gbé ìgbésẹ̀ akíkanjú lati kọ ìwà ìjẹgàba àti irẹjẹ àwọn obìnrin ní ọwọ́ àwọn Ọba ìlú àti àwọn agb̀gbè wa, fún àláfia àti ìlọsíwaju àwọn obìnrin àti ìdílé.
- Ìtàn fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn obìnrin ọlọ́jà ti jẹ́ àlátìlẹyìn owó fún àwọn ẹbí, àwọn olósèlú, ètò ìdìbò, síse àkànse isẹ́ ìdàgbàsókè fún àwùjọ, àti ètò ìparí ìjà ni àwùjọ.
- Àwọn Ìyálọ́jà ní àtijọ́ jẹ́ ohuǹ tó lágbára fún síse ipinnu lórí àwọn ètò tó kan gbogbo ará ìlú, ní pàtàkì jùlọ, àwọn ọ̀rọ̀ tó kan àwọn obìnrin, ìdílé, mẹ̀kúnnu àti ìgbèríko. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà àtìlẹ́yiǹ wọn se kókó fún olùdíje sí ipò iselu ní ẹsẹ̀ kùkù.

Sùgbọ́n, ní àsìkò yi, ìjọba ní ẹlẹ́kajẹ̀ka àti gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ ìlú kan ti gbàgbé gbogbo akitiyan àti ipa tí a kó fún ìdúrósinsin, ìlọsíwájú àti ìdàgbàsókè àwùjọ, ọrọ̀ ajé, ìsèlú àti àláfíà ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀ àti orílèdè wa. Ìjọba ti gbáwa sẹgbẹ, wọ́n pawátì, wọn dẹ́yẹ si wa, wọn ko fún wa laye tó tọ́ síwa nínú ètò ìsèlú agbègbè, ìpínlẹ̀ àti orílèdè wa.

## ii. **Ipò Tí-A-Wa Loni – Òtítọ̣ Wa: Àdojúkọ Àìní – àti- Ìfún – Pin-Pin.**

## Ìjìjàdù Ìse Olórí Laarin Àwọn Ìyálọ́jà


Orisun: Jonathanimafidor, Ibadan Oyo state 2024


- Ìpo Ìyálọ́jà se pàtàkì nínú àsà àti ọrọ̀ ajé agbègbè, ìlú àti orílèdè, sùgbọ́n ní àsikò yii, ipò yi ti di yẹpẹrẹ nítorí àìlèfẹnukò lórí ẹni tí ipò yi tọ́ sí láàrin àwọn ọlọ́jà obìnrin ní pàtàkì jùlọ ní gbogbo ọjà tó wà nilu Ìbàdàn, èyí ti kó àkùdé bá iyì àti ọ̀wọ̀ tó wà lára ipò Ìyálọ́jà ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, láti se asojú àti olùjàfẹ́tọ àwọn obìnrin ọlọ́jà àti gbogbo obìnrin ìgbèríko.

- Wàhálà ìwọ ko jùmí, èmi ko jù ọ́, ti jẹ́ kí ẹgbẹ́ onísòwò pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ, àìsí ìsọ̀kan yi ti sọ wọ́n di yẹpẹrẹ lọ́dọ̀ ìjọba, gẹ́gẹ́bí asojú àti ẹgbẹ́ pàtàkì tó
- lẹ́nu nínú ètò ìsèlù, àdínkù si rírí ìrànwọ́ owó okòwò lọ́dọ̀ ìjọba, ilé-ìfowópamọ́, àwọn olùdókòwò ní abẹ́lé àti àwọn àkànse ètò ìjọ́ba ní ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀, kò si àpọ́nlé mọ́ fún gbogbo akitiyan àwọn obìnrin onísòwò lórí ìmúdúró, ìmúgbòòrò ọrọ̀ ajé àti ìlọsíwájú àwùjọ.



## Ìdẹ́yẹsí Nínú Ètò Ìsèlú àti Ìmúgbòòrò Àwujọ

- Àwọn obìnrin onísòwò ni ìjọba ti dẹ́yẹsí nínú kíkópa nínú òsèlú gẹ́gẹ́bí asojú àwọn onísòwò àti àwọn obìnrin ìgbèriko ní gbogbo ẹ̀ka ìjọba.
- Àwọn ìjọba ìbílẹ̀ àti àjọ elétò ìlu ń se ìpinnu ààtò ìlú láì gba ìmọ̀ràn àwọn Ìyálọ́jà àti àwọn onísòwò, wọn ń fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú akitiyan àti ojúse wọn lórí ìdàgbàsókè ọrọ̀ ajé àti ìlọsíwájú àwọn obìnrin àti àwùjọ.



## Àìsí Ààbò tó Péye fun Ọrọ̀ Ajé

- Púpọ̀ nínú àwọn obìnrin onísòwò ni kò ní ànfààní sí ẹ̀yáwó tó rọrùn, àti àyè ìtajà tó ní ààbò to péye nínú ọjà.
- Àwọn onisòwò alábọ́dé láàrin wa ń dojúkọ àìsí owó-okòwò, ẹ̀kúnwó tó gun gbogbo ọjà kó àwọn onísòwò obìnrin sí wàhálà àìrí ọjà ta bíi ti àtèyìnwá. Eléyìí se àfikún òsì, ebi àti ìyà fún awọn ọmọ àti ìdílé.

## Àwọn Nkàn Amáyédẹrùn Tó Ti Bàjẹ́

- Ní àwọn ọjà wa, kò si nkan amáyédẹrùn bii omi tó mọ́ gaara, iná ẹ̀lẹ́ntíríkì, ilé ìyàgbẹ́, ilé ìdalẹ̀sí, àjọ paná-paná, ilé ìwòsàn alábọ́dé, ilé ìtọ́ju ọmọdé, ilé ìfarapamọ́sí fún òjò, òòrùn tàbí ìjì líle, ọ̀nà eléruku, gọ́tà ìgbàlódé àti bẹ bẹ lọ.
- Púpọ́ nínú àwa obìnrin onísòwò ni a jẹ́ olùgbọ́bùkátà (ìdá àádọ́rin nínú ọgọ́run) fún àwọn ọmọ àti ìdílé wạ. Ìjọba kò se àpónlé àti kóríyá fún wa lórí ojúse wa gẹ́gẹ́ bí olùgbẹ́bíró ní àwùjọ wa.




- Ní gbogbo ìgbà ni a ń kojú wàhálà lílé kúrò ní ìsọ̀ wa, tàbí wíwó ilé ìtajà wa ní ọ̀nà tí kò bá òfin mu, àti kíkó ọjà lọ́ sí àdúgbò míràn ní òjiji, láì pèsè ìsọ̀ míràn tí a ń kó lọ, tàbí fífún wa ní owó gbà mábínú. Ìsòro yi ń fa ìfàsẹ́yìn fún okòwò, àlékún ìsé, òsì, ní àfikún ó ń fa abùdé fún àláfíà àti ìgbáyégbádùn àwọn ọmọ ẹgbẹ́ àti ìdílé won.

## iii. Àwọn Kókó Ohun tí a Fẹ́:

Àwọn Ọ̀rọ̀ Ìyànjú fún gbogbo Ìyálọ́jà: Gba Agbára Padà pẹ̀lú Ìlànà.

- À n ti ara wa lẹ́yìn, a o ki ń se àtakò ara wa. Àseyọrí Ìyálọ́jà kan gbọ́dọ̀ jẹ́ ìyangàn gbogbo wa. Iyì àti ìmọlẹ̀ pọ fún gbogbo olórí to n se ìfẹ́ àwọn ènìyàn rẹ̀.
- A ń parí ìjà pẹ̀lú iyì àti ọgbọ́n. A n yanjú gbogbo ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ ọmọ ìyá ní kọ̀rọ̀ pẹ̀lú ọkàn kan.

*Nítorípé tí àwọn Ìyálọ́jà bá wà ní ìsọ̀kan, kò sí obìnrin kan kan tó ma kù lẹ́yìn. Tí a bá dúró papọ̀ kò ní sí ọjà Kankan tí yo kojú ìdẹ́yẹsí. Tí a bá fohùn sọ̀kan, gbogbo àgbáyé gbọ́dọ̀ tẹ́tí síwa. Ẹ jẹ́ kí ìsọ̀kan wa jẹ́ ohun tí wọn o fi máa rántí wa lẹ́yìn ọ̀la. Ẹ jẹ́ kí mí ìjẹ́ ọmọ ìyá kan náà jẹ́ agbára wa.*

- Jẹ́ Ohùn àwọn obìnrin, má jẹ ariwo àwọn olósèlú, kọ̀ láti jẹ́ irinsẹ́ láti kó ìbò jọ, nígbà tí wọn kò rántí àwọn àdojúkọ obìnrin. Lo ipò olórí rẹ ní ìgbèríko, lai fi àwọn olósèlú bojú.
- Fi gbogbo agbára rẹ sin ọmọnìyàn. Àwọn obìnrin onísòwò, ọlọ́jà, pẹ̀lú gbogbo àwọn obìnrin ìgberíko tí wọ́n rí ẹ ní aláseyọrí ni orísun agbara rẹ. Se àpọ́nlé wọn, máa se agbẹnusọ fún wọn, kí ìdẹ̀kùn le bá ìgbésíayé wọn.
- Rí dájú pé àwọn olórí tí a dìbò yàn, láì fi ti ẹgbẹ́ òsèlú se, síkà gbogbo àdéhùn wọn fún àwọn obìnrin onísòwò ati ọlọ́jà. Bá wọn sọ̀rọ̀ akíkanjú, lórí èròngbà ará ìlú.
- Jẹ olùpèpè fún bùúre-làáre gbogbo ètò àti ẹ̀tọ́ lórí ọrọ̀-ajé. Pe ìpè fún àwọn ètò amúlùúdùn alábọ́dé tó já gaara fún gbogbo obìnrin, ètò owó-orí tí kò ní ìyànjẹ nínú, ètò èyáwó tó rọrùn, and ètò ìdánilẹ́kọ fún àwọn obìnrin olùdásẹ́sílẹ̀. Sọ ipò rẹ di irinsẹ àtúnse fún ọmọnìyàn.
- Fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn Ìyálọ́jà míràn àti àwọn olórí ẹgbẹ́ obìnrin gbogbo, nínú ọjà, ìlú, àti àwọn ìpínlẹ̀ míràn fún ìsọ̀kan. Àgbájọwọ́ la fi ń sọ̀yà, ìsọ̀kan àwọn obìnrin nìkan ló le kojú ìsòro tó ti di bárakú ti gbogbo obìnrin ń dojú kọ ní gbogbo àgbáyé, ní pàtàkì jùlọ ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́.
- Máa rántí ; pé ìwọ kìí se ẹrú fún agbára, olùkọsílẹ̀ ìtàn ni ọ́. Àwọn obìnrin alábárìn, àwọn tó n tẹ̀lé ọ, àti àwọn tó ń bọ̀ lẹ́yìn rẹ ni olùró adé rẹ ní



**KAN SÁRÁ SÍ ÌYÁLỌ́JÀ**

"Ó ń rìn níbi tí àrá ti kúnlẹ̀, Adé rẹ̀ kìí se idẹ, bí kò se ìfẹ́-inú àwọn obìnrin.
Ohùn akọni lárìn àwọn ọkùnrin,
Gbẹ̀du ìlù lárìn ọjà,
Iná lábẹ́ ìkòkò ọbẹ̀, Abúgbẹ̀mù lẹ́yìn agbára tó dákẹ́ rọ́rọ́.
Kìí bẹ̀rẹ̀ lábẹ́ agbára kò tọ́,
Òhun gan-an ni Agbára – tó fẹsẹ̀ múlẹ̀ dain-dain, a fi òógùn rin lójò-lẹ́ẹ̀rùn.
Ẹni tí àwọn abiyamọ àti àwọn onísòwò a gbé sókè
Ẹni tó ń tẹríba fún Ọba àti ìjòyè pẹ̀lú àpọ́nlé
Ẹni tó ń fi òtítọ́ gbadé lórí àwọn asebi.
Ẹni tó ń rìn pẹ̀lú àánú
Ẹyinjú rẹ̀ ni ìdájọ́ òdodo ń gbé
Ìyálọ́jà kìí se òjísẹ́, òhun gan-an ni isẹ́
Kìí se ọmọ-isẹ́, òhun gan-an ni orísun
Ìyálọ́jà O,

Òrìsà nínú ìró àti ọgbọ́n

Ìyá gbogbo ìgboro

Atùpà àwọn tí kò lẹ́nu ọ̀rọ̀

Dúró gìdìgbà

Torípé nínú rẹ ni orílẹ̀dè ti ń mí.

Olùkọ oríkì – arábìnrin: Ere Amachree

## B. ÌPÈ LÓRÍ GBOGBO ỌRỌ̀ ÀÌGBỌ́ – ARA – ẸNI – YÉ TÓ Ń SẸLẸ̀ LÓRÍ OYÈ ÌYÁLỌ́JÀ ÌPÍNLẸ̀ ỌYỌ́

**1. Ìpè fún ìgbésẹ̀ kíá-kíá láti yanjú gbogbo èdè-àìyé-èdè tó wa lórí oyè Ìyálọ́jà Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́.**

* A pè Ìjọba láti gbé ìgbésẹ̀ kánmọ́-kánmọ láti wá ojútùú si gbogbo aáwọ tó rọ̀ mọ́ oyè ìyálọ́jà ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, pẹ̀lú ìlànà gbangba làsá ń ta, àjọro, àti gbogbo ọ̀nà tó bá òfin mu.

* A pe Gómìnà ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ Ọlọ́lájùlọ Onímọ̀ẹ̀rọ Olúsèyí Mákindé; kí wọ́n se àfihàn ẹnìkan soso gẹ́gẹ́ bí Ìyálọ́jà Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, fún ìfìdímúlẹ̀ ìsọ̀kan àwọn onísòwò; pẹ̀lú ìse-asojú rere fún àwọn onísòwò, àti fífi òpin sí pín-pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ àwọn ẹgbẹ́ onísòwò, èyí tó ń fa akùdé fún ìbére fún ìjọba rere lọ́wọ́ àwọn adarí wa.

**2. Se Ìrólágbára Ojúse àwọn Ìyálọ́jà àti Àwọn Ẹgbẹ́ Onísòwò ní Ìgbèríko**

* A pè fún àyẹ́sí àti ìrólágbára àwọn Ìyálọ́jà pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ onísòwò tó wà ní ìgbèríko gẹ́gẹ́bí asojú àwọn ẹgbẹ́ onísòwò, àti rírí dájú pé wọ́n ń dásí ọ̀rọ̀ nínú ìgbìmọ̀ ìsàkóso ẹgbẹ́ ọlọ́jà.

* A pè fún ìsèjọba ẹlẹ́kùn-jẹkùn nínú ìgbìmọ̀ ọlọ́ja tó ga jùlọ, kí àwọn Ìyálọ́jà tó wà ní ìgbèríko le bèère fún irànlọ́wọ́ àti nkàn àmúlò lọ́wọ́ ìjọ́ba fún àwọn ọjà wọn.

**3. Se Àgbékalẹ̀ Ètò fún Píparí Èdè-Àìyédè**

* A bèèrè fún ìdásílẹ̀ àjọ tó dá dúró fún píparí ìjà láàrin àwọn onísòwò, pẹ̀lú àtìlẹ́yìn ìjọba, fún ìdènà ìjà ọlọ́jọ́ pípẹ́.

**C. SÍSE ASOJÚ ÀTI ÌLỌ́WỌ́SÍ**

* A bèèrè fún ìyànsípò asojú àwọn obìnrin ọlọ́ja sínú àwọn ìgbìmọ̀ olùdámọ̀ràn fún ìjọba ìbílẹ̀ àti ìpínlẹ̀.

* A bèrè fún àyẹ́sí àti àtìlẹ́yìn fún àwọn ẹgbẹ́ àwọn obìnrin onísòwo, àti àwọn olórí wọn nínú gbogbo ètò ìjọba.

* A bèrè fún ìbọ̀wọ̀ fún ìmọ̀ràn àwọn obìnrin onísòwò nínú àgbékalẹ̀ àwọn àkànse ètò tó dá lórí kárà-kátà, àtúntò ìlú, síse déédé láàrin ọkùnrin àti obìnrin, ati ìlọsíwájú ọrọ̀-ajé.




ÌYÁLỌJÀ – 'Ẹni Tí Kò Gbọdọ̀ Sẹrú Ọ̀gá Kankan'
Kìí se ọmọ-ọ̀dọ̀ fún àwọn ọba ní kóòtù òfeègé
Kìí sì se olùsàjọ fún ìrètí àwọn obìnrin
Láti ná bí owó-sílè ní ìdí àpótí-ìbò
O kìí se ọmọ-ọ̀dọ̀ àmúlò fún agbára
Ìwọ gan-an ni agbára

Fi wọ́n sílẹ̀ kí wọ́n mọ́ fi ẹ́ jókòó láàrin wọn
Àfi kí wọ́n jẹ nínú ọlá àkójọ rẹ,
Kí wọ́n paré tí ẹ bá ti dìbò tán,
Wọ́n á fi àwọn ọmọbìnrin rẹ sílẹ̀
Ìwọ kìí se alárinà wọn sí ọjà –
Ìwọ gan-an ni àrá-ọjà

Dìde Ìyálọ́jà,
Orúkọ rẹ tóbi ju àmúkọrin àwọn olósèlú lọ lásìkò ìdìbò
O kọjá olùgbàlejò fún àwọn ìlérí òfo,
Ìwọ ni ìdájọ́ òdodo fún iye tí wọ́n ń ta isu,
Ìwọ ni ohùn àti olùgbèjà fún àwọn opó, àti àwọn onísòwò,
Ìwọ ni ìgbẹ́kẹ̀lé fún gbogbo ìlú

Ìwọ kìí se ìránsẹ́ fún àwọn aláìníkanse ọkùnrin. Abiyamọ totọ ni ọ́, Kiniun oloola ijù, Atáyése –
Ìwọ kìí se ọmọ-ọ̀dọ̀, ìwọ ni olùmọ àwọn àyànmọ́.

Mọ́ gba olósèlú láyè láti fi ẹrẹ̀ yí orúkọ rẹ, kí wọ́n dojú òtítọ́ rẹ bolẹ̀,
Ìjẹ́ olóòtọ́ rẹ wà fún àwọn ènìyàn nìkan,
Ìjẹ́ olóòtọ́ rẹ wà fún ìmísókè-sílẹ̀ ọja, àti fún àwọn tí ń sunkún tí ẹnìkankan kò gbọ́ igbe ẹkún wọn.

Ìyálọ́jà, máa rántí ẹni tí o jẹ́,
Kìí se àyànmọ tàbí ojúse rẹ láti sin ẹnikankan,
A bí ọ sáyé láti jẹ́ olórí àti alákóso àwọn ènìyàn.

Alákójọ Ewì - Arábìnrin Ere Amachree

**ÌLỌSÍWÁJÚ ÀWỌN OHUN AMÁYÉDẸRÙN**



- A bèrè fún ìpèsè àti ìtọ́jú omi tó mọ́ gaara, ìtọ́jú àyíká, gọ́tà, ati ìtọjú ẹ̀gbin ní gbogbo ọjà.
- A bèrè fún kíkọ́ àwọn ìṣọ̀ ìtajà-onílẹ̀kùn alábọ́dé, ilé ìkẹ́rùpamọ́sí, ọ̀nà tó já gaara, àti ìpèsè iná-ìríran fún àbò àyíká ní gbogbo ọjà.
- A bèrè fún ìpèsè àbò tó péye, pẹ̀lú lílò ẹ̀rọ kámẹ́rà  tó-ń –ká ohùn pẹ̀lú àwòrán sílẹ̀ láti dẹ́kun olè, ìdẹ́rùbani àti ìjọ̀ngbọn.
- A bèrè fún ìpèsè ilé-isẹ pẹ̀lú irinsẹ paná-paná, láti dènà ìjànbá iná nínú ọjà.

**E. ÈTÒ OWÓ-ORÍ TÍ KÒ GUNPÁ ÀTI ÈTÒ ÌKÓRAẸNINIJANU**




* A bèrè fún ìmúkúrò sísan owó-orí alátunsan-tunsan; ati gbígbà àwọn owó tí kò ní ìtumọ̀ lọ́wọ́ àwọn ọlọja.

* A bèrè fún àlàkalẹ̀ tó fàyè gba òtítọ́ láìsí kọ́lọ́fín, nínú ètò owó gbígbà, pẹ̀lú rìsiiti, àti ànfààní fún fífi ẹ̀hónú hàn.

*A bèrè fún ìdẹ́kun ìwà jàndùkú àti gbígbà owó lọ́nà ìyànjẹ nínú ọjà.

**F. ÌPÈSÈ ÈTÒ FÚN Ẹ̀YÁWÓ ÀTI ÌDÁNÍLẸKỌ NÍPA OKOÒWÒ**

* Ètò ẹ̀yáwó tí èlé rẹ̀ kò gajù fún àwọn obìnrin onísòwò.

* Ìrólágbára ẹgbẹ́ alájẹsẹ́kù pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ fún ìforúkọ sílẹ̀ fún gbígbà ìwé-ẹ̀rí lọ́dọ̀ ìjọba.

* Ètò ìdánilẹ̀kọ́ lórí ìmọ̀ nípa ìsuná àti ìlọsíwájú okòwò.

**G. ÀBÒ ÀTI  ÌDÁJỌ́**




* A bèrè fún àmúdópin gbogbo ìwà ìpáǹle sí àwọn obìnrin onísòwò láti ọ̀dọ̀ àwọn agbófinró, àwọn ọlọ́pa ọjà, àti àwọn olùgbowó nínú ọja.

* Ìdásílẹ̀ àjọ olùpẹ̀tùsíjà pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn àjọ amòfin tí kìí se ti ìjọba.

* Ìseàmúlò àwọn òfin tó ń pè fún ìdabóbò àwọn obìnrin fún ìdènà ìwà-ipá sí obìnrin nínú ọjà.

**ÌLERA ÀTI ÀBÒ ÀWÙJỌ**





- Ìse àfikún àwọn obìnrin onísòwò sínú ètò adójútòfò-ìlera àti àwọn àkànse ètò ìrónilágbára fún àwọn aláìní.
- Ìpèsè ilé-ìwòsàn alágbéká, ilé-ìtọ́jú ọmọ-ọwọ́/ilé-ìseré-ọmọdé, ìpàgọ́ àwọn elétò-ìlera nínú ọjà, lórí ọ̀rọ̀ àwọn ìyálọ́mọ àti alafia lẹ́nu isẹ́.
- Ìrànlọ́wọ́ fún àwọn arúgbó onísòwò pẹ̀lú ìkópa nínú ètò ìfowópamọ́ fún àsìkò ìfẹ̀yìntì àti àkànse ètò àwùjọ fún àwọn aláìní.

**I. Ẹ̀KỌ́ ÀTI ÌRÓNILÁGBÁRA**



- Ìdánilẹ́kọ̀ òòrè-koore fún àwọn onísòwò obìnrin lórí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, owó-orí, ìmọ́tótó, àtúnse àwọn èrè-oko, àti ìmọ̀ nípa ètò ọ̀gbìn ti ìgbàlódé.
- Ìkówólé àwọn ètò ẹ̀kọ́ kọ́mi-n-kọ́ọ fún àwọn obìnrin onísòwò pẹ̀lú àwọn ọ̀dọ nínú ọjà.
- Pípe àwọn obìnrin ọlọ́ja sí àwọn àpèjọ to ń jíròrò lórí àwọn àkànse ètò fún ìlọsíwájú àwùjọ, ìfikuǹlukùn, àti àwọn ọ̀rọ̀ tó ní se pẹ̀lu òsèlú.

**J. ÌKANISÍ ÀTI ÀPỌ́NLÉ**





* Ìkanisí àwọn Ìyálọ́jà àti àwọn ètò olórí – àsà nínú ọjà, gẹ́gẹ́ bí alájọsepọ̀ nínú kíkó àwùjọ pọ̀ fún ìkópa nínú ìsèjọba rere.
* Síse ayẹyẹ àyájọ́ ọjọ́ àwọn obìnrin onísòwò ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ fún ìmọrírì ipa tí won ń kó nínú àwùjọ.

- Support for aging traders through contributory pension schemes and community care initiatives.

**IV. ÀWỌN ÀFOJÚSÙN WA**

A ní àfojúsùn láti:




- Ìsọ̀kan àti ìdúrótiraẹni láàrin àwa obìnrin onísòwò, láìfi ti ẹ̀yà, ẹ̀sìn, tàbí ìyàtọ nínú ẹgbẹ́ òsèlú wa.
- Ìbásepọ̀ àláfíà pẹ̀lú gbogbo ẹlẹ́gbẹ́-jẹgbẹ́.
- Àkóyawọ́, déédé, àti ìtiraẹni léyìn nínú egbẹ́ àti gbogbo àsepọ̀ wa.

**V. ÀKÓTÁN**

Ìwé-Ìfẹnuko yii, kii se àkọsílẹ̀ àwọn ohun ti a ń fẹ́ lásán, ó jẹ́ ojúse tí òfin àti ẹ̀kọ́ ọmọnìyàn làkalẹ̀ fún gbogbo ẹ̀ka ìjọba láti dìde sí àwọn




ìpènijà tó ń dojúkọ àwọn obìnrin onísòwò, tí wọn ń kópa tó jọjú fún ìmúdúró ètò ọrọ̀-ajé, ìgbé-ẹbí-ró, ati ìdúró sinsin àwùjọ  láti dìde sí àwọn ìpènijà tó ń dojúkọ àwọn obìnrin onísòwò, tí wọn ń kópa tó jọjú fún ìmúdúró ètò ọrọ̀-ajé, ìgbé-ẹbí-ró, ati ìdúró sinsin àwùjọ Yorùbá. Àwa o tọrọ agbe. A n bèrè fún dédé, àpọ́nlé, àti Ànfàní láti jẹ́ alábápín nínu ìsèjọba, àti gbogbo àkànse ètò fún ìdàgbàsókè àwa obìnrin ní ìgbèríko.

Àwa, obìnrin onísòwò ti ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, ti setán lati gba àyè nínú ìtàn lati sètò ọjọ́ iwájú nibi tí akitiyan, ohùn, àti ẹ̀tọ́ wa ti se kókó. Kí àwọn asíwájú wa gbọ́ wa. Kí ìgbésẹ̀ sit ẹ̀le.


A pe Gómìnà ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Ilé ìgbìmọ̀ asòfin, àwọn alaga ìjọba ìbílẹ̀, àwọn kọmísánnà, ilé isẹ́ ìyàwó gómìnà, àwọn ọba alayé, àti gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn kí wọ́n dásí ìwé àfẹnukò láti gbé ìgbésẹ̀ kánmọ́-ń-kíá fún ìrólágbára àti ìlọsíwájú àwọn obìnrin onísòwò. Ìlọsíwájú àti àseyọrí ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ dúró lórí ìrólágbára àwọn obìnrin onísòwò.

## Ìfọwọ́sí:

Àwọn obìnrin onísòwò fọwọ́sí Ìwe àfẹnukò yii.

.

“ A KÌÍ SE ONÍSÒWÒ LÁSÁN, A N KÚN ORO AJÉ, A N ÀGBÉRÓ ORO AJÉ, A BÈRÈ FÚN IYÌ, ÀSEPO, ÀSOJÚ ÀTI ÌDÁJO.



Pelú Àtìleyìn:

HEINRICH BÖLL STIFTUNG

ABUJA